# Ogun Jíjà àti Ìṣèlú ní Ilẹ̀ Yorùbá: Àtúpalẹ̀ Àlọ́-Onítàn *Ọba Aláwùúre*

**Aráròba Táíwò Ọpẹ́yẹmí**
*Department of Linguistics and African Languages*
*Ọbafẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ile-Ifẹ̀, Ọ̀ṣun State, Nigeria*
*taiwoyemijessie@gmail.com*

## Àṣamọ̀

*Ọ̀kan-ò-jọ̀kan iṣẹ́ ni àwọn onímọ̀ ti ṣe lórí ogun jíjà àti ètò ìṣèlú ìbílẹ̀ Yorùbá. Inú àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí ni a ti rí ìtàn nípa ogun jíjà nílẹ̀ Yorùbá láyé ọjọ́un àti ètò ìṣèlú wọn. Irúfẹ́ àwọn ìtàn báwọ̀nyí lè jẹ́ lọ́nà tààrà, wọ́n sì lè ṣe àgbékalẹ̀ wọn sí inú ewì, ìtàn ìwásẹ̀, ìtàn akọni, eré onítàn, òwe àti àlọ́-onítàn. Àfojúsùn iṣẹ́ yìí ni láti ṣe àyẹ̀wò ipa tí ogun jíjà ní lórí àwùjọ Yorùbá láyé àtijọ́ àti láti jíròrò lórí àwọn ẹ̀kọ́ pàtàkì tí ó sodo sínú ètò ìṣèlú ìbílẹ̀ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àlọ́ onítàn wọn. Àkọlé àlọ́ tí a lò ni Ọba Aláwùúre. Àlọ́ yìí jẹ́ ọ̀kan lára détà tí a gbà láti ẹnu àgbàlagbà kan tí ó ní ìmọ̀ kíkún nípa àlọ́ pípa. Tíọ́rì Karl Marx ni a lò fún àtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí. Lára àwọn nǹkan tí tíọ́rì Marx pe àkíyèsí sí ni ètò-ìṣèlú àti ètò-ọrọ̀ ajé. Iṣẹ́ yìí ṣe àfihàn bí ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ṣe máa ń bu omi paná àṣìlò agbára, ó sì fi hàn pé àmúlò ìpèdè náà, 'wíwo lẹnu awo í wo' jẹ́ atọ́nà fún àṣeyọrí nínú ìgbógunti ìwà ìbàjẹ́. Orí èrò tí ìwádìí yìí gúnlẹ̀ sí ní pe àlọ́-onítàn Yorùbá jẹ́ ọ̀kan lára àwọn àká tí a ti lè ṣe àwárí àṣà àti ìṣe àwùjọ Yorùbá ayé àtijọ́.*

**Kókó ọ̀rọ̀:** Ogun Jíjà, Ìṣèlú, Àlọ́-onítàn, Ọba Aláwùúre.

## Ìfáárà

Onírúurú iṣẹ́ ni àwọn onímọ̀ ti ṣe lórí àlọ́-onítàn Yorùbá tí ó jẹ́ ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Bí àpẹẹrẹ, àwọn kan fún àlọ́-onítàn ní oríkì, àwọn kan ṣe àkójọpọ̀ rẹ̀, iṣẹ́ wà lórí ìpínsísọ̀rí àlọ́, ètò-ìṣèlú inú àlọ́, àlọ́ onítàn nínú orin fújì, tó fi mọ́ ìwúlò àlọ́-onítàn ní àwùjọ Yorùbá. Díẹ̀ lára àwọn onímọ̀ yìí ni Babalọlá (1973), Babalọlá (1979), Ògúnpolú (1986), Agbájé (2013), Aráròba (2015), Oyèdèjì (2017) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Orímóògùnjẹ́ (1996:13) ṣàlàyé pé "Àlọ́ jẹ́ àròsọ lásán tí kìí ṣe òótọ́, wọ́n kàn fi ń kọ́ni lẹ́kọ̀ọ́ ìwà. Ó kún fún ìtàn apanilẹ́rìn-ín àti ìtàn ọlọ́gbọ́n ẹ̀wẹ́ ní àwùjọ ni." Nígbà tí ó ń jíròrò lórí ìjẹyọ àlọ́ onítàn nínú orin ajẹmẹ́sìn Mùsùlùmí, Rájí (2014:248) sọ pé: "Àgbékalẹ̀ àwọn ìtàn wọ̀nyí yàtọ̀ díẹ̀ sí ti àgbékalẹ̀ ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ ojú-ayé gidi nípa sísọ àsìkò, ọjọ́, oṣù àti ọdún." Àkíyèsí onímọ̀ yìí tọ̀nà nítorí pé kò sí àsìkò kan pàtó tí a lè tọ́ka sí pé ìṣẹ̀lẹ̀ inú àlọ́-onítàn wáyé. Àmọ́, gẹ́gẹ́ bí àlàyé Orímóògùnjẹ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àlọ́ jẹ́ ìtàn àròsọ lásán, tí kìí sìí ṣe òótọ́, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀kọ́ ni a máa ń rí fàyọ nínú àwọn àlọ́ wọ̀nyí. Bí àpẹẹrẹ, àlọ́-onítàn tí ìjíròrò inú bébà yìí dá lé lórí kò fún wa ní àkókò tàbí déètì kan pàtó nípa àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú rẹ̀, kódà, kò sọ orúkọ àwọn ọba méjèèjì tí a bá pàdé nínú rẹ̀ fún wa. Síbẹ̀, ìtàn inú àlọ́ yìí ṣe àfihàn bí àwọn Yorùbá ṣe ń jagun àti bí wọ́n ṣe ń ṣèlú ní àwùjọ wọn ní ayé àtijọ́. Bákan náà, a tún rí àwọn ẹ̀kọ́ pàtàkì fàyọ fún ètò-ìṣèlú òde-òní. Rájí (2014:248) pe ìtàn inú àlọ́ Yorùbá ní "àwòrán àwùjọ Yorùbá

pọ́nńbélé." Àkíyèsí Rájí yìí tọ̀nà nítorí pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àlọ́-onítàn Yorùbá ni àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ Yorùbá ayé àtijọ́ gùn lé.

### Ìjẹyọ Ogun Jíjà àti Ìṣèlú nínú Àlọ́-Onítàn *Ọba Aláwùúre*

Àkọlé àlọ́-onítàn tí a ṣe àtúpalẹ̀ rẹ̀ nínú pépà yìí ni *Ọba Aláwùúre*. Àlọ́ onítàn jẹ́ orísìí ìtàn àròsọ kan tí ọ̀pọ̀ ènìyàn kà sí àjogúnbá láti ọ̀dọ̀ àwọn baba ńlá wọn; wọ́n gbàgbọ́ pé irúfẹ́ ìtàn báyìí lè kọ́ àwọn ọmọdé ní ẹ̀kọ́ nípa ìwà rere. Ọba tí ìtàn tí a pe àkọlé rẹ̀ ní *Ọba Aláwùúre* dá lé lórí fẹ́ràn láti máa gbógun ja àwọn ìlú tí ó wà ní àyíká rẹ̀. Kò sí ìgbà tí ó bá ké sí àwọn jagunjagun rẹ̀ láti lọ kógun ja àwọn ìlú tàbí abúlé mìíràn, tí ìlú wọn kìí ṣẹ́gun. Ọba yìí jẹ́ alágbára, ó sì lóògùn abẹnu gọ̀ǹgọ̀ lọ́wọ́. Gbogbo ọdẹ ìlú ni ọba yìí ti sọ di ọmọ ogun, ó máa ń lo àwọn ọ̀dọ́ ìlú nílòkulò, ojoojúmọ́ làwọn kan lára àwọn ọ̀dọ́ wọ̀nyí lọ ń roko ọba, àwọn mìíràn ń kọ̀pẹ fọ́ba, àwọn mìíràn sì ń kọ́ṣẹ́ ogun jíjà. Lóòrèkóòrè ni ọba yìí ń pàṣẹ pé kí àwọn ọmọ ogun ìlú òun lọ máa gbógun ti àwọn ìlù kéèkèèké tí ó yí wọn ká. Bí wọ́n bá ti ṣẹ́gun àwọn ìlú wọ̀nyí tán, wọn a gbà wọ́n mọ́ tiwọn, wọn a kẹ́rú, wọn a kẹ́rù. Bí wọ́n bá pe àwọn ìlú tó tóbi díẹ̀ níjà, kíá ni ọ̀pọ̀ nínú àwọn ìlú wọ̀nyí yóò túbá, tí wọn yóò sì gbà láti bọ́ sí abẹ́ àjàgà wọn láìsí ogun tàbí ìjà. Kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ ọba yìí bẹ̀rẹ̀ síí fi bí agbára rẹ̀ ṣe pọ̀ tó hàn nípasẹ̀ ogun tí ó ń gbé ja àwọn ìlú ńlá àti àwọn ìlú kéréje, tí ó sì ń ṣẹ́gun wọn. Yàtọ̀ fún ìlò àwọn ohun ìjà ogun bí àdá, ọ̀kọ̀ àti ọfà, àwọn jagunjagun ọba yìí a tún máà lo àwọn oògùn ajẹ́-bí-idán bíi egbé, kánàkò, ìṣújú

àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Kò sí ìlú tí ó jẹ́ gbéná wojú wọn. Àkókò ìṣàkóso ọba yìí kò rọgbọ fún àwọn ọkùnrin ìlú rárá. Ìdí ni pé bí kábíyèsí ṣe ń gbẹ́sẹ̀ lé wúńdíá tó ti ní àfẹ́sọ́nà, bẹ́ẹ̀ ló ń gbẹ́sẹ̀ lé abilékọ. Àwọn ìjòyè gba ọba ní ìmọ̀ràn pé kì ó tẹ̀ ẹ́ jẹ́jẹ́, kàkà kí kábíyèsí ronú lé ohun tí wọ́n sọ lórí, níṣe ló kọ etí ọ̀gbọin sí i.

Ní àsìkò tí à ń wí yìí, ìlú kan wà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Ìlúdùn. Ìlú tí ó tóbi gbáà ni ìlú yìí. Ọba Ìlúdùn jẹ́ onínúure, ó lókìkí, ó sì gbajúmọ̀ púpọ̀, ètò ọrọ̀ ajé Ìlúdùn gbámúṣé, àwọn oníṣòwò sì ń ṣe ìdókòwò wọn níbẹ̀. Gbogbo nǹkan ń lọ déédé fún àwọn ará ìlú nítorí pé wọ́n ní ètò. Ìlúdùn ní ogúnlọ́gọ̀ jagunjagun nítorí wọn a máa kọ́ àwọn ẹrú tí wọ́n bá ṣe àkíyèsí pé wọ́n ní agbára àti làákàyè ní iṣẹ́ ogun jíjà. Àwọn ìjòyè kábíyèsí ni wọ́n máa ń jẹ́ ọ̀gágun fún ìsí ọmọ ogun kọ̀ọ̀kan, orí ẹṣin ni àwọn ìjòyè wọ̀nyí sì ti máa ń jagun ní tiwọn. Nígbà tí òkìkí Ìlúdùn kàn dé ọ̀dọ̀ ọba aláwùúre tí àlọ́-onítàn yìí dá lé lórí, tí ó sì fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọba Ìlúdùn ní ọlá, òkìkí àti agbára ju òun lọ fíìfíì, ọba aláwùúre bẹ̀rẹ̀ sí fi ojú bíńtín wo ọlá ati ọlà tí ó kó jọ, àwọn ìlú tí ó ti jẹ gàba lé lòrí kò tó nǹkan lójú rẹ̀. Ojoojúmọ́ ni ó ń ronú lórí ọ̀nà tí yóò gbé e gbà àti ọgbọ́n tí yóò dá láti dàbí ọba Ìlúdùn. Kódà, ìfẹ́ ọkàn ọba yìí ni pé kí òkìkí rẹ̀ kàn dáadáa ju ti ọba Ìlúdùn lọ.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé agbára ọba Ìlúdùn pọ̀ tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ́, òun kìí sábà gbógun ja àwọn ìlú mìíràn nítorí àti ní agbára kún agbára, àlọ́-onítàn yìí fi yéni pé ọba Ìlúdùn a máa dìde ogun nígbà tí ọba ìlú tí kò tó okùn bàtà rẹ̀ í tú bá yájú sí i nípa lílẹ

ìdí àpò pọ̀ pẹ̀lú ìlú mìíràn láti dìtẹ̀ tàbí kọ̀ jálẹ̀ láti singbà tàbí san ìṣákọ́lẹ̀. Àìkìí sábà jagun yìí ni ó fà á tí ètò ọrọ̀-ajé Ìlúdùn fi ń lọ geere.

Ní ọjọ́ kan, ọba aláwùúre pe gbogbo oníṣègùn àti àwọn awo ìlú rẹ̀ jọ sí ìpàdé pàjáwìrì kan. Nínú ìpàdé yìí ni ọba ti fi èròǹgbà rẹ̀ hàn láti di ọba tí ó lókìkí jù lọ láàárín àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ tó àwọn awo ìlú létí. Nígbà tí àwọn awo gbọ́ èyí, wọ́n foríkorí, lẹ́yìn náà, wọ́n rọ kábíyèsí pé kí ó fún àwọn ní ọjọ́ méje péré láti ṣiṣẹ́ lé ohun tí ó bá wọn sọ lórí.

Nígbà tí ọjọ́ méje pé, àwọn awo wọ̀nyí yan àwọn aṣojú láti lọ mú ọṣẹ àwúre fún kábíyèsí. Wọ́n sọ fún ọba pé kì ó tọ́jú ọṣẹ náà di ọjọ́ kejì, kí ó sì máa ṣọ́ ìgbà tí oòrùn yóò yọ láwọsánmà, ṣé ojú ò kúkú níí mọ́ kí ọ̀ọ̀yẹ̀ má là, oòrùn ò sì ní í yọ kí ọmọ aráyé fi ọwọ́ bò ó lójú. Wọ́n ṣe àlàyé fún kábíyèsí pé igba gbẹ́rẹ́ ni yóò sín sí ibi èyíkéyìí tí ó bá wù ú ní ara rẹ̀, wọ́n sì kìlọ̀ fún un pé gbẹ́rẹ́ yìí gbọ́dọ̀ pé igba àti pé gbàrà tí oòrùn bá ti yọ ní àwọsánmọ̀ ni kí ọba bẹ̀rẹ̀ sí sín gbẹ́rẹ́ náà.

Lóòótọ́, nígbà tí ilẹ̀ ọjọ́ kejì mọ́, ọba gúnwà sí orí ìtẹ́ rẹ̀, ó ń retí ìgbà tí oòrùn máá yọ, ní gẹ́rẹ́ tí oòrùn yọ báyìí, kíá ni ọba mú abẹ́fẹ́lẹ́ tí ó sì bẹ̀rẹ̀ síí sín gbẹ́rẹ́ sí ara rẹ̀. Bí ọba ti ń sín àwọn gbẹ́rẹ́ yìí, bẹ́ẹ̀ ni ẹ̀jẹ̀ ń ṣe yàlà lára rẹ̀. Nígbà tí gbẹ́rẹ́ pé igba, kábíyèsí ki ọṣẹ àwúre mọ́lẹ̀, ó bọ́ sí ilé ìwẹ̀, ó hó ọṣẹ sára, ó bẹ̀rẹ̀ síí wẹ̀. Bí kábíyèsí ṣe ń wẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni ara ń ta á kíkankíkan, bì ara ṣe ń ta á, bẹ́ẹ̀ ló ń jó o, bí ìgbà tí agbọ́n bá ń tani lọ̀rọ̀ ṣe rí lára kábíyèsí. Nígbà tí kò lè mú un mọ́ra

mọ́, ọba bẹ́ síta láti inú ilé ìwẹ̀, ó forí lé ìta gbangba, ó sì bẹ̀rẹ̀ sí gbé ara yílẹ̀. Léyẹ kò sọkà, àwọn ará ìlú ti péjọ lé e lórí, àwọn awo tó ṣe oògùn àwúre sì wà níbẹ̀ pẹ̀lú.

Bí àwọn ará ìlú ṣe ń ṣe kàyéfì nípa ìṣẹ̀lẹ̀ abàmì yìí, bẹ́ẹ̀ ni Olúawo ìlú kọjú sí wọn tí ó sì ṣe ìròyìn nìpa bí iṣu ṣe kú àti bí ọ̀bẹ ṣe bẹ ẹ́ fún wọn. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, "ọgbọ́n ẹnìkan kò tó, bẹ́ẹ̀ sì ni ìmọ̀ràn ẹnìkan kò jọ bọ̀rọ̀." Ó ní lẹ́yìn tí ọba ṣe ìpàdé pẹ̀lú awọn tán ni àwọn dá a bí ọgbọ́n, tí wọ́n fi eéjì kẹ́ẹ́ta ṣe ọṣẹ tí wọ́n pè ní ọṣẹ àwúre fún kábíyèsí aláṣejù yìí. Bí olú awo ṣe ń sọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ ni kábíyèsí ń yíra mọ́lẹ̀ tí ó sì ń joró ikú, báyìí ni ọba alágbára di ẹni tí kò ní agbára mọ́, lẹ́yìn-ọ̀rẹyìn, ó kú ikú ẹ̀sín, àwọn ará ìlú sì ṣe ṣíọ̀ rẹ̀. Lẹ́yìn tí Olúawo ti sọ gbogbo bí wọ́n ṣe di ọ̀rọ̀ yìí láwo fún àwọn ará ìlú tán ni ó dá orin, àwọn ará ìlú sì ń gbe orin náà. Orin ọ̀hún lọ báyìí pé:

Lílé: O jọba tán, o tún ń wàwúre
Ègbè: Ohun gbogbo é mọ̀ í tólè lọ́rùn, ohun gbogbo
Lílé: O rójú tán, o ń wá àìrójú kiri
Ègbè: Ohun gbogbo e mọ̀ í tólè lọ́rùn, ohun gbogbo
Lílé: Ẹni bá kánjú jỌlọ́run
Ègbè: Ohun gbogbo é mọ̀ í tólè lọ́rùn, ohun gbogbo
Lílé: Á jìyà, á jewé iyá
Ègbè: Ohun gbogbo é mọ̀ í tólè lọ́rùn, ohun gbogbo
Lílé: O tún ń wàwúre
Ègbè: Ohun gbogbo e mọ̀ í tólè lọ́rùn, ohun gbogbo

Láti ìgbà tí òǹrorò ọba yìí ti fi ìwà ìmọ-tara-ẹni-nìkan àti ìjẹgàba rẹ̀ fa àjálù sí orí ara rẹ̀, tí èyí sì mú kì ó wàjà láìpé ọjọ́, ni ó ti di àṣà ní ìlú yìí fún àwọn àgbàlagbà láti máa sọ ìtàn ọba aláwùúre fún àwọn tí wọ́n bá fẹ́ẹ́ gorí ìtẹ́ láti fèyí kọ́gbọ́n. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, "ẹni tó jìn sí kòtò, ó kọ́ ará yòókù lọ́gbọ̀n."

## Àlàyé nípa Tíọ́rì àmúlò fún Iṣẹ́ yìí

Tíọ́rì Karl Marx ti a mọ̀ sí "Marxism" ni a lò fún àtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí. Àfojúsùn àwọn onítíọ́rì yìí ni pé iṣẹ́-ọnà òǹkọ̀wé ṣe é lò gẹ́gẹ́ bí irin iṣẹ́ láti tú àṣírí àwọn aládàáńlá ní àwùjọ. Èyí ni pé òǹkọ̀wé le è ṣe agbátẹrù bí àwùjọ ṣe lè ra ara rẹ̀ padà tí èyí yóò sì mú ìtura bá mùtúmùwà. Tíọ́rì Marx tan ìmọ́lẹ̀ sí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ nípa títẹpẹlẹ mọ́ ọn pé ọwọ́ àwọn oríṣìí ẹ̀dá kan láwùjọ ni agbára wà, tí àwọn wọ̀nyí sì ń jẹ gàba lé ìṣọ̀wọ́ àwọn ẹ̀dá yòókù lórí.

Ìjẹgàba a máa wáyé nínú ètò ọrọ̀-ajé àti ìṣèlú, èyí ló fà á tí tíọ́rì yìí ṣe fẹ́ kí òǹkọ̀wé lo iṣẹ́ ọnà rẹ̀ yálà láti mú kí àyípadà ọ̀tun dé bá àwùjọ ni tàbí kí ó tilẹ̀ ṣe àmúkúrò ìwà yìí pátápátá. Àwọn onítíọ́rì yìí gbàgbọ́ nínú èrò-báyéṣerí (ideology), wọ́n sì ri pé ó wúlò láti ṣe àtúpalẹ̀ iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀.

Ògúnṣínà (1987:37-39) ṣàlàyé pé lójú Karl Marx, ọrọ̀ ajé olókoòwò aládàáńlá (capitalism) jẹ́ ìjẹgàba àwọn ọlọ́rọ̀ tí wọ́n fi ń darí àwùjọ fún àǹfààní ara wọn. Ó sọ pé, gẹ́gẹ́ bíi ti àwọn tó ti wà ṣáájú, ìyẹn ètò ìṣàkóso "ọba-ló-nilẹ̀"

(monarchical rule), ìṣèjọba ọrọ̀-ajé olókoòwò aládàáńlá yóò ṣe okùnfà ìkùnsínú láàárín àwọn ẹgbẹ́ tí ó wà ní àwùjọ, èyí yóò sì mú kí irúfẹ́ ìṣèjọba yìí kọjá lọ. Òmíràn tí a mọ̀ sí "Socialism" yóò sì rọ́pò. Ètò ìṣèjọba alájọni ni a mọ èyí sí.

Marx àti ojúgbà rẹ̀ tí a mọ̀ sí Engels rí àṣà kíkó ọrọ̀ jọ gẹ́gẹ́ bí kẹ̀kẹ́ tó n yí itàn àwùjọ padà láti ìgbà dé ìgbà. Marx gbà pé ètò ọrọ̀-ajé jẹ́ àtẹ òye ẹ̀dá àti ìtàn àwùjọ. Ó ní èyí ni okùnfà ìfagagbága tí ó máa ń wáyé láàárín ẹlẹ́gbẹ́jẹgbẹ́ ní àwùjọ.

Bákan náà, nígbà tí ó ń jíròrò lórí àṣà àwùjọ, Marx pe tíọ́rì rẹ̀ kan ní "Conflict Theory" (Tíọ́rì Aáwọ̀). Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2014:65) sọ pé:

> Ìlànà tí aáwọ̀ ń gbà wáyé ni ìwà tàbí ìṣe ẹ̀dá-ènìyàn tàbí ọ̀pọ̀ ènìyàn kan sí ẹlòmíràn tàbí àwọn ẹ̀dá-ènìyàn mìíràn... ìwà ọ̀kánjúà, ìmọtara-ẹni-nìkan, olè, àìbìkítà fún bí ohun tí a bá ṣe ti lè kan ọmọnìkejì tàbí àwùjọ mìíràn (légbò) sì lè fa aáwọ̀.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí ṣe àwọn àlàyé yìí nígbà tí ó ń jíròrò lórí Tíọ́rì Aáwọ̀. Àwọn ìwà abèṣe tí ó mẹ́nu bà gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ jẹ́ àwọn ìwà tí ọba aláwùúre hù nínú àlọ́-onítàn tí a gbé yẹ̀wò nínú pépà yìí. Àwọn ìhùwàsí yìí ni ó fa ìkùnsínú àwùjọ sí kábíyèsí. Àwọn ẹgbẹ́ awo sì ṣe àmúlò àǹfààní tí wọ́n ní láti jìjàgbara.

Yàtọ̀ fún èyí, tíọ́rì Marx gbà pé láti ayé àwùjọ tí a mọ̀ sí "ọba ló nilẹ̀" (Monarchy) ni àwùjọ ẹ̀dá ti ń dàgbà bọ̀. Àlọ́-onítàn tí a tú palẹ̀ nínú iṣẹ́ yìí ṣe àfihàn ètò-ìṣèlú ìbílẹ̀

Yorùbá, nínú èyí tí a ti rí ìṣàkóso tọbatìjòyè. Nítorí náà, a gbà pé tíọ́rì yìí yóò wúlò fún iṣẹ́ àtúpalẹ̀.

Ní àkótán, ọ̀rọ̀ nípa ètò ọrọ̀-ajé àwùjọ jẹ yọ nínú àlọ́-onítàn yìí. Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2014:52) sọ pé “ọrọ̀-ajé ati ìṣèlú ló ṣe atọ́nà fún ìbágbépọ̀ ẹ̀dá.” Ó ní, “àwọn onítíọ́rì Karl Marx gbà pé ọrọ̀-ajé ni ó bí ọ̀rọ̀-ìṣèlú.” Àkíyèsí Ọ̀pẹ́fèyítìmí nípa èrò àwọn onítíọ́rì Marx yìí fihàn pé a kò lè sọ̀rọ̀ nípa ọrọ̀-ajé láì sọ̀rọ̀ nípa ìṣèlú, a kò sì lè sọ̀rọ̀ nípa ìṣèlú, ká má sọ̀rọ̀ nípa ètò ọrọ̀-ajé. A ní ìdánilójú pé tíọ́rì Karl Marx yóò wúlò púpọ̀ fún àtúpalẹ̀ iṣẹ́ ìwádìí yìí.

## Ìlò Tíọ́rì Karl Marx fún Atúpalẹ̀ *Ọba Aláwùúre*

Akínyẹmí (1987:18) sọ pé: “Tíọ́rì ni ìlànà tàbí òfin tí ó jẹ́ atọ́nà fún lámèètọ́ nígbà tí ó bá fẹ́ yẹ iṣẹ́ lítíréṣọ̀ kan wò, yálà lítíréṣọ̀ náà jẹ́ alohùn tàbí àkọsílẹ̀.” Tíọ́rì tí a ó ṣe àmúlò fún àtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí ni tíọ́rì Karl Marx. Awọn kókó-ọ̀rọ̀ tí a ṣe àkíyèsí pé ó jẹ yọ nínú àlọ́-onítàn *Ọba Aláwùúre* ni: Èrò nípa Báyéṣerí, Ìjẹgàba, Agbára ati ìjìjà-gbara.

***Èrò nípa Báyéṣerí:*** Èrò nípa báyé ṣe rí jẹ́ èrò tí ó sábà máa ń jẹ yọ nínú ìrònú, ìpèdè àti ìwà àwọn alágbára tàbí àwọn arẹ́nijẹ sí àwọn mẹ̀kúnnù, wọ̀n máa ń jẹ́ kí àwọn mẹ̀kúnnù ní ìmọ̀lára pé ìpín àwọn mẹ̀kúnnù wọ̀nyí rọ̀ mọ́ ìyà nípa ọ̀nà tí wọ́n gbà ń bá wọn lò, yálà lọ́rọ̀ ẹnu tàbí ìhùwàsí. Bákan náà, àwọn mẹ̀kúnnù náà máa ń ní ìgbàgbọ́ nípa èrò báyé ṣe ri, èyí tí ó máa ń kì wọ́n lákìwọ̀ láti bèèrè fún ẹ̀tọ́ wọn.

Nínú àlọ́-onítàn *Ọba Aláwùúre*, èrò nípa báyéṣerí farahàn nínú ìrònú àti ìhùwàsí ọba. Èrò tí àwọn tí ó wà lókè láwùjọ sábà máa ń ní ni pé bí Ọlọ́run ṣe dá ayé ni kí ọwọ́ àwọn máa lọ sókè sí, kí àwọn aláìní sì túbọ̀ máa rì sínú ìṣẹ́ tí wọ́n wà. Èrò yìí hàn nípa bí ọba aláwùúre ṣe ń sa gbogbo ipá rẹ̀ láti ní ohun gbogbo àti láti wà lókè téńté, láìka ipa tí èyí yóò ní lórí àwọn ará ìlú sí tàbí bìkítà nípa ìnira tí yóò kó bá wọn.

Yàtọ̀ fún èyí, èrò nípa báyé ṣe rí tún farahàn nípa bí àwọn tí ọba aláwùúre jọba lé lórí kò ṣe lè ṣe ohunkóhun láti gba ara wọn sílẹ̀ lọ́wọ́ ìnira tí ọ̀nà ìgbàṣèlú ọba aláwùúre kó bá wọn, wọ́n rí ara wọn gẹ́gẹ́ bí ìṣọ̀wọ́ àwọn ènìyàn tí kò lẹ́nu ọ̀rọ̀ láwùjọ, ó sì tún ṣeé ṣe kí wọ́n lérò pé bí àwọn bá dìde láti lòdì sí ìwà ìjẹgàba ọba, ọ̀rọ̀ lè bẹ́yìn yọ, omi sì lè tẹ̀yìn wọ ìgbín lẹ́nu. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, "ẹni tí kò tóni í nà, tí ń dènà de ni, àjẹkún ìyà ni yóò jẹ." Síbẹ̀, ó yẹ kí àwọn ènìyàn wọ̀nyí rántí pè, "bí a bá lé ewúrẹ́ kan ògiri, ewúrẹ́ yóò buni jẹ." Ẹ̀rí fi hàn pé "bí kábíyèsí ṣe ń gbẹ́sẹ̀ lé wúńdíá tí ó ti ní àfẹ́sọ́nà náà ló tún ń gbẹ́sẹ̀ lé abilékọ."

Àìlè gbé ìgbésẹ̀ tako ìwà àìtọ́ tí ọba ń hù yìí ṣe àfihàn ojú tí àwọn tí a ń rẹ́jẹ láwùjọ fi máa ń wo ara wọn gẹ́gẹ́ bí aláìlágbára, tí wọ́n sì rí àwọn tí ń rẹ́ wọn jẹ gẹ́gẹ́ bí àwọn tí wọ́n ní agbára lọ́dọ̀, wọ́n sì tún rí wọn ní ìrí pé kò sí ẹni tí ó lè yẹ̀ wọ́n lọ́wọ́ wò.

***Ìjẹgàba***: Ọ̀pẹ́fèyítìmí (1997:43) sọ pé "Gàba nípa… ìṣèlú múmú láyà tíọ̀rì Karl Marx." Ìyẹn ni pé ọ̀rọ̀ nípa ìṣèlú àti lílò

tí àwọn òṣèlú ń lò ó láti jẹ gàba lé àwùjọ lórí ló jẹ tíọ́rì Karl Marx lógún. Ó tún fi kún un pé "ìyípadà tàbí ìfòpinsí ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni wọ́n ń gún àwọn òǹkọ̀wé ní kẹ́ṣẹ́ láti fi iṣẹ́ ọnà wọn wá fún àwùjọ wọn."

Lọ́pọ̀ ìgbà, gàba nípa ìṣèlú a máa kó wàhálà, ìdààmú, ìnira àti ìpọ́njú bá àwọn ènìyàn àwùjọ. Àyọlò ìsàlẹ̀ yìí ṣe àfihàn itú tí ọba tí ó yẹ kí ó ṣe àbójútó àwọn ará ìlú lọ́nà rere ń fi wọ́n pa:

> Ó ń gba ilẹ̀ lọ́wọ́ onílẹ̀. Ó sì ń lo gbogbo ọ̀dọ́ ìlú nílòkulò, kábíyèsí… ń gbẹ́sẹ̀ lé wúńdíá tí ó ti ní àfẹ́sọ́nà… ó tún ń gbẹ́sẹ̀ lé abilékọ.

Láìsí àní-àní, àyọlò òkè yìì jẹ́ kí a mọ̀ pé nǹkan ò rọgbọ fún àwọn tí ọba aláwùúre ń ṣàkóso lé lórí, kódà, a rí àpẹẹrẹ ìfọwọ́ ọlá gbáni lójú nínú bí ó ṣe ń gba ilẹ̀ lọ́wọ́ onílẹ̀, tí ó ń lo àwọn ọmọ ọlọ́mọ nílòkulò, tí ó sì tún ń gba aya aláya. Àjàgà wíwọni lọ́rùn ni èyí jẹ́ fún àwọn tí ọba yìí ń jọba lé lórí.

***Agbára:*** Àkíyèsí Karl Marx ni pé àṣìlò agbára ló máa ń jẹ́ okùnfà ìjẹgàba. Èyí ni pé àwọn tó bá ní agbára, tí wọ́n sì yàn láti lò ó nílòkulò lò máa ń jẹ gàba lé àwọn ẹni tí kò ní agbára lórí. Ìṣèlú jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn okùnfà agbára láwùjọ. Àṣìlò agbára jẹ yọ nípa bí ọba aláwùúre ṣe di ẹrù wíwúwo ru àwọn tó wà lábẹ́ rẹ̀ láìka ìṣẹ́ àti ìyà tí èyí yóò kó bá wọn sí. Àyọlò ìsàlẹ̀ yìí ṣe àpèjúwe irúfẹ́ agbára tí ọba yìí ní:

> Ó jẹ́ alágbára
> Ó lóògun abẹnu gọ̀ngọ̀ lọ́wọ́
> Ó sì nífẹ̀ẹ́ sí ogun jíjà púpọ̀

Àyọlò yìí fi hàn pé gbogbo ara kìkì oògùn ni ọba aláwùúre. A ri fàyọ pé “ó nífẹ̀ẹ́ sí ogun jíjà púpọ̀”, èyí kò sì yani lẹ́nu nítorí pé bí agbára bá ti pọ̀ lápọ̀jù, a máa gunni.

***Ìjìjàgbara:*** Èrò Karl marx àti àwọn ènìyàn rẹ̀ ni pé àwọn ènìyàn àwùjọ gbọ́dọ̀ gbára dì láti jìjàgbara kúrò lọ́wọ́ àwọn arẹ́nijẹ. Ìdí ni pé bí ènìyàn bá wà nínú ìgbèkùn ìjẹgàba, bí ẹni wà nínú àtìmọ́lé ni, olúwarẹ̀ kò níí ní òmìnira. Akitiyan ìjìjàgbara jẹ yọ nínú àlọ́ yìí nígbà tí àwọn awo ìlú dá a bí ọgbọ́n láti fòpin sí ìwà ìjẹgàba àti àṣìlò agbára tí ọba aláwùúre gùn lé. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀nà ẹ̀rọ ni àwọn awo ìlú gbe ìjìjàgbara wọn gba, bí wọ́n ṣe fẹ́ kó rí bẹ́ẹ̀ náà lórí, ìdí ni pé èròǹgbà wọn láti rẹ́yìn ọba aláwùúre wa sí ìmúṣẹ. Èyí sì kọ́ni lẹ́kọ̀ọ́ pé nígbà mìíràn, ọgbọ́n a máa wúlò nínú ìjìjàgbara ju agbára lọ. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, “ọgbọ́n ju agbára.”

## Ètò Ìṣèlú inú Àlọ́ gẹ́gẹ́ bí Awògbè fún Ètò Ìṣèlú Yorùbá Ayé Àtijọ́

Kín ní ń jẹ́ ìṣèlú? Fánilọ́lá (1990:17) sọ pé “kò sí bí a ti ṣe fẹ́ẹ̀ wò ó tí a kò níí sọ̀rọ̀ lórí pínpín agbára. Èyí ni pé àwọn wo ni yóò lo agbára, àti irú agbára bẹ́ẹ̀… wíwá agbára àti lílò rẹ̀ ni a lè pè ní ìṣèlú.” Àkíyèsí Fánilọ́lá yìí ní ìfẹṣẹ̀múlẹ̀ nínú àlọ́ tí a ń yẹ̀wò nínú iṣẹ́ yìí.

Ní àwùjọ Yorùbá ayé àtijọ́, ọba àti àwọn ìjòyè ní ń mú ipò iwájú nínú ètò ìṣèlú, àwọn awo ìlú, tó fi mọ́ àwọn jagunjagun náà kò gbẹ́yìn. Àlọ́ *Ọba Aláwùúre* ṣe àfihàn ọba, àwọn ìjòyè, àwọn awo àti àwọn jagunjagun. A rí àwọn ọba méjèèjì tí a ṣe alábàápàdé nínù àlọ́ yìí gẹ́gẹ́ bí alágbára.

Láyẹni (1978:192) sọ pé “ìlú kan lè gbógun ti ìkejì, láti fi agbára rẹ̀ hàn.” Ó tún fi àpẹẹrẹ ti ọ̀rọ̀ rẹ̀ lẹ́yìn báyìí pé “Àwọn ẹ̀yà Yorùbá tí ó ja ogun amú-ìlú-mìran-mọ́-tẹni ní Èkìtì, Ifẹ̀ ati Ìjẹ̀bú.” Àlọ́ onítàn yìí ṣe àfihàn bí ọba aláwùúre ṣe ń gbógun ti àwọn ìlú mìíràn, tí ó sì ń kó wọn mọ́ tirẹ̀ láti fi agbára rẹ̀ hàn àti láti mú kí àwùjọ rẹ̀ gbòòrò sí i. Oyèwọlé (1996:4) ṣàlàyé pé “ìṣèlú jẹ́ ọgbọ́n tàbí òye tí a lè fi ṣe àkóso kan tí ó jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà láàrin àwọn ẹ̀yà kan. Ó ní, “nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìdarí àwọn ènìyàn, ọ̀rọ̀ nípa agbára kò níí ṣàì máà wáyé.” Ètò-ìṣèlú ọba Ìlúdùn ṣàpẹẹrẹ bí èyí tí ó pọ̀ jù nínú àwọn ọba ilẹ̀ Yorùbá ayé ọjọ́un ṣe máa ń ṣe ohun gbogbo létòlétò. Wọn a máa ṣe àmúlò ọgbọ́n ati làákàyè, kí ìṣàkóso wọn baà lè tu àwọn ará ìlú lára. Àlọ́-onítàn yìí fi Ìlúdùn hàn gẹ́gẹ́ bí àwùjọ tí ó létò púpọ̀, ọba Ìlúdùn kìí dédé dìde ogun láì ní ìdí pàtàkì, àlọ́ yìí fi yé wa pé ètò ọrọ̀ ajé Ìlúdùn gbámúṣé. Lóòótọ́, àfihàn agbára jẹ yọ nínú ètò ìṣàkóso ọba Ìlúdùn, ṣùgbọ́n kò lo agbára tirẹ̀ ní ìlòkulò bíi ti ọba aláwùúre.

Àwọn ohun tí àlọ́-onítàn yìí pe àkíyèsí sí gẹ́gẹ́ bí àwọn ohun ìjà tí àwọn ọmọ-ogun ń lò ni àdá, ọ̀kọ̀, ọfà àti oògùn. Yàtọ̀ fún èyí, a rí àwọn tí ń gẹṣin jagun. Ìwádìí fi hàn pé àwọn ohun ìjà wọ̀nyí ni àwọn ọmọ Yorùbá ń lò lójú ogun ní ìgbà àtijọ́. Láyẹni (1978:194) ṣàlàyé pé:

> Láti ìgbà tí Ọ̀yọ́ ti dó sí ilẹ̀ tí ó tẹ́jú ni wọ́n ti máa gẹṣin jagun… Kí ó to di pé Òyìnbó dé Ìwọ̀ Oòrùn Áfríkà, ni àwọn babańlá wa ti ńja ogun, …Ọfà, ọ̀kọ̀, ògbó, àdá, agẹdẹngbẹ, ni wọ́n fi

> ńjà. Wọ́n tún máa ńlò oògùn pẹ̀lú, bíi ìṣújú, kánàkò, egbé àti ohùn… nígbà tí ogun bá kó ìlú kan tì, oògùn ni wọ́n máa fi ńtú ìlú náà ká.

Àyọlò yìí jẹ́rìí sí pé àkùrọ̀ àwọn ọmọ Yorùbá ti lómi tẹ́lẹ̀ kí òjò tó rọ̀, tí a bá ń sọ nípa ohun ìjà, oríṣìíríṣìí ohun ìjà ni àwọn ọmọ Yorùbá fi ń jagun kí òyìnbó tó kó ìbọn dé.

Bákan náà, àlọ́-onítàn yìí ṣe àfihàn rẹ̀ pé àwọn ọ̀dọ́ ìlú ní ń roko, tí wọ́n ń kọ̀pẹ, tí wọ́n sì tún ń ṣe àwọn oríṣìí nǹkan mìíràn fún ọba. Oyètádé (2009:16) sọ pé "àwọn ènìyàn ń wárí fọ́ba ni àti pé gbogbo ìlú ni ó máa ń gbọ́ bùkátà ọba." Èyí fi bí àpọ́nlé tí àwọn ènìyàn ìlú ń ṣe fọ́ba láyé ọjọ́un ṣe pọ̀ tó hàn. Àjàyí àti Atọ́lágbé (2005:345) ṣàlàyé nípa "pàtàkì, ipò ọba ní ayé àtijọ́." Wọ́n ní, "ọba kìí rán ẹnikẹ́ni níṣẹ́ kí onítọ̀hún kọ̀ ọ́, nítorí pé tọba làṣẹ, ọba sì ba lórí ohun gbogbo ni." Àkíyèsí àwọn onímọ̀ yìí jẹ́ kí a mọ ìdí tí àwọn ọ̀dọ́ ìlú àti àwọn òbí wọn kò fi kùn, tí wọn kò sì janpata nígbà tí àwọn ọ̀dọ́ wọ̀nyí ń fi ojoojúmọ́ jíṣẹ́ fún ọba aláwùúre. Yàtọ̀ fún èyí, àlọ́-onítàn yìí fi yé wa pé "gbogbo ọdẹ ìlú ni ọba yìí (ọba aláwùúre) ti sọ di ọmọ ogun." Dáramọ́lá àti Jéjé (1967:144) sọ pé "àwọn ọdẹ ni a máa í yàn gẹ́gẹ́ bí jagunjagun tàbí ọmọ-ogun ní ilẹ̀ Yorùbá… Ní àkókò ogun ni gbogbo ọdẹ ìlú ńdi ọmọ-ogun." Àjùwọ̀n (2017:95) ṣe àkíyèsí pé "kìí ṣe gbogbo àwọn jagunjagun ni wọ́n n yan iṣẹ́ ogun jíjà láàyò láyé àtijọ́. Ọ̀pọ̀ nínú àwọn jagunjagun náà ni wọ́n máa ń jẹ́ ọdẹ tàbí àgbẹ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ayé wọn." Àkíyèsí àwọn onímọ̀ yìí fi hàn pé ipa pàtàkì ni

àwọn ọdẹ ìlú ń kó nínù ètò ìṣèlú ayé àtijọ́. Àwọn ló ń jagun, àwọn ló ń ṣọ́ ìlú, tí wọ́n sì tún ń dá ààbò bò ó.

Gẹ́gẹ́ bí a ti mẹ́nu bà ṣáájú, àwọn ìjòyè ìlú ni wọ́n ń kún ọba lọ́wọ́ nínú ètò-ìṣèlú àwùjọ ní ilẹ̀ Yorùbá. Àwọn ìjòyè wọ̀nyí ló súnmọ́ kábíyèsí jù. Àjàyí àti Atọ́lágbé (2005:344) sọ pé "àwọn ìjòyè ni abọ́bajíròrò, wọn kìí jìnnà sí ààfin ọba, àwọn ni wọ́n máa ń yí ọba ká." Nígbà tí ọba Aláwùúre bẹ̀rẹ̀ síí jayé fàmí-létè-kí-n-tutọ́, àwọn ìjòyè rẹ̀ ni wọ́n kìlọ̀ fún un pé kí ó rọra ṣe. Àlàmú (2013:40) sọ pé "àwọn ìjòyè yìí ni wọ́n máa ń péjú sí ààfin láti jíròrò lórí àwọn ohun tó ń lọ ní ìlú àti ọ̀nà tí àlàáfíà yóò ṣe jọba kí ìlú fi rọrùn láti gbé fún mùtúmùwà."

Kò sí àní àní pé iṣẹ́ takuntakun ni àwọn awo ìlú náà ṣe nígbà tí ọba aláwùúre kọ̀ láti gba ìmọ̀ràn tí àwọn ìjòyè fún un. Ọṣẹ tí wọ́n pè ní ọṣẹ àwúre fún kábíyèsí ni wọ́n lò láti rẹ́yìn rẹ̀. Ipa tí àwọn awo ìlú kó nínú àlọ́ yìí ni a lè fi wé ojúṣe àwọn olóyè tí ó lágbára jù lọ láàárín àwọn ìjòyè ọba ní àwùjọ Yorùbá. Àwọn ìjòyè wọ̀nyí a máa kìlọ̀ fún ọba tí ó bá ń gbé ìgbésẹ̀ láti gun igi ré kọjá ewé, bí ọba bá kọ etí dídi sí ìkìlọ̀ wọn, wọ́n ní agbára láti lé e kúrò lórí ìtẹ́ tàbí pàṣẹ pé kí ó ṣígbá.

Ọlájubù (1978:91) ṣàlàyé pé:

> "Àwọn ìjòyè tí ó ga jù ni à ńpè ní ìwàrẹ̀fà. Mẹ́fà ni wọ́n sábà máa ńjẹ́, àwọn ni ó lágbára jù… Bí wọ́n bà lòdì sí ọba lápapọ̀ kò sí nǹkan tí ọba lè ṣe… Irúu wọ́n sì wà ní ìlú gbogbo ní ilẹ̀ Yorùbá... Àpapọ̀ọ wọn lágbára ju ọba lọ."

Gẹ́gẹ́ bí àyọlò òkè yìí, a rí àfihàn bí àwọn ẹgbẹ́ awo ìlú ṣe ní agbára ju ọba aláwùúre tí àlọ́ yìí sọ pé ó jẹ́ alágbára, ó sì lóògùn abẹnu gọ̀ǹgọ̀ lọ́wọ́. Àwọn awo inú àlọ́-onítàn yìí ni ìgbésẹ̀ tí wọ́n gbé fara jọ irúfẹ́ èyí tí àwọn ìwàrẹ̀fà máa ń gbé nígbà tí ọba bá ń ni àwọn ará ìlú lára tàbí hu oríṣìí ìwà abèṣe mìíràn. Ìyàtọ̀ kan gbòógì tí a ṣe àkíyèsí pé ó wà láàárín ìgbésẹ̀ tí àwọn awo inú àlọ́ yìí gbé àti irúfẹ́ ìgbésẹ̀ tí àwọn ìwàrẹ̀fà máa ń gbé lòdì sí ọba aláṣejù ni pé ọ̀nà ẹ̀rọ ni àwọn awo inú àlọ́ yìí gbé ìdájọ́ tiwọn gbà, ṣùgbọ́n 'sàn-án là á rìn' ni àwọn ìwàrẹ̀fà ilẹ̀ Yorùbá máa ń fi ìdájọ́ tiwọn ṣe, kò sí bojúbojú lọ́rọ̀ ti wọn.

Síwájú síi, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àkóso rẹ̀ kò bá wọn lára mu, àwọn ará ìlú ọba aláwùúre ṣúgbàá rẹ̀ nínù ìlàkàkà láti mú ìlọsíwájú bá ìlú wọn. Àlọ́-onítàn yìí sọ̀rọ̀ nípa bí àwọn ọ̀dọ́ ìlú ṣe ń lo ara wọn nínú iṣẹ́ ọba, àwọn ọdẹ ìlú kò sí fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú ogun jíjà, bí ọba ti ń késí wọn, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ń dá a lóhùn. Bákan nàà ni ọmọ ṣorí ní Ìlúdùn. Ohun tí ó mú kí ètò-ìṣèlú ọba Ìlúdùn yàtọ̀ sí ètò-ìṣèlú ọba aláwùúre ni pè ọba Ìlúdùn ní tirẹ̀ mú kí ohun gbogbo rọ mùtúmùwà lọ́rùn. Wọ́n fi ètò sí àwọn nǹkan tí wọ́n ń ṣe. Àlọ́-onítàn yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ètò ọrọ̀-ajé Ìlúdùn dára. Ohun tí a lérò pé ó fa èyí ni pé ìwọ̀ntúnwọ̀nsì ni ọba wọn ń ṣe nǹkan. Bí àpẹẹrẹ, a ri fàyọ pé kìí fi ìgbà gbogbo ṣígun, ìdí nìyí tí kò yani lẹ́nu pé ètò ọrọ̀-ajé wọn ń lọ déédé. A tún ri fàyọ pé tèwetàgbà ni ọwọ́ wọn ń dí fún iṣẹ́ ṣíṣe ní Ìlúdùn. Èyí fi hàn pé wọn ò dá ètò ìṣàkóso dá ọba àti àwọn ìjòyè rẹ̀ nìkan. Aráròba (2015:36) ṣàlàyé pé:

> Fún ìlú láti tùbà tùṣẹ, ìfọwọ́sowọ́pọ̀ gbọ́dọ̀ wà láàárín tọbatìjòyè tó fi mọ́ àwọn ará ìlú. Àjọṣe ni ọ̀rọ̀ ìṣèlú fún mùtúmùwà, èyí fi hàn pé ètò ìṣèlú kò yọ ẹnikẹ́ni sílẹ̀, àwọn olórí kàn wà nípò láti ṣojú àti láti sin ìlú ni.

Àyọlò òkè yìí kín òwe Yorùbá tó sọ pé "ọ̀tún wẹ òsì, òsì wẹ ọ̀tún ni ọwọ́ fi í mọ́" lẹ́yìn. Bí àwọn ènìyàn tí kò sí ní ìgbọ́nnu ìṣàkóso bá kọ ìhà kò-kàn-mí sí iṣẹ́ ìlú, kò ní rọrùn fún irú àwùjọ bẹ́ẹ̀ láti tẹ̀síwájú. Ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àwọn ará ìlù pẹ̀lú tọbatìjòyè tí ó jẹ yọ nínú àlọ́-onítàn yìí jẹ́ ìtọ́kasí nípa bí ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àwọn ará ìgbàanì pẹ̀lú àwọn alákòóso wọn ṣe máa ń so èso rere.

## Ètò-Ìṣèlú inú Àlọ́-Onítàn Yorùbá gẹ́gẹ́ bí Alóre fún Ètò-Ìṣèlú Òde-Òní

Aráròba (2015: xiv) sọ pé "ètò-ìṣèlú inú àlọ́-onítàn Yorùbá ni ètò ìṣèlú àwùjọ ilẹ̀ Yorùbá ayé ọjọ́un gùn lé." Ó fi kún un pé "ètò-ìṣèlú inú àlọ́ tẹpẹlẹ mọ́ àtubọ̀tán adarí rere, ó ṣe àfihàn onírúurú ìjìyà tí ń bẹ fún àwọn ọ̀jẹ̀lú." A fara mọ́ èrò yìí nítorí pé àtúpalẹ̀ àlọ́-onítàn tí a gbé yẹ̀wò nínú pépà yìí ṣe àfihàn ìjẹyọ ètò-ìṣèlú ìbílẹ̀ àwùjọ Yorùbá láyé àtijọ́. Ohun tí ó ṣẹlẹ̀ sí ọba aláwùúre tún jẹ́rìí sí pé àṣegbé kò sí fún ọba tó ń jayé ní ìjẹkújẹ.

Àǹfààní tí kò lẹ́gbẹ́ ni ẹ̀kọ́ inú àlọ́ *Ọba Aláwùúre* lè ṣe fún àwọn tó dipò aṣáájú mú láwùjọ. Bí Olódùmarè bá fi ni sípò àṣẹ, èèyàn kò gbọ́dọ̀ rí irú àǹfààní bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ bí mímọ̀ọ́ṣe rẹ̀, aṣáájú tó ní àròjinlẹ̀ gbọ́dọ̀ rí ipò rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ibi tí Ọlọ́run

fúnra rẹ̀ fi òun sí kí ó sì tún mọ̀ pé òun ní láti jíyìn fún Olódùmarè bí òun ṣe lo ipò náà. Bákan náà, aṣáájú gbọ́dọ̀ ní ẹ̀mí ìtẹ́lọ́rùn, ìdí ni pé àìní-ìtẹ́lọ́rùn máa ń sin ni lọ sí oko ìparun ni, gẹ́gẹ́ bí a ti rí nínú ohun tí ó ṣẹlẹ̀ sí ọba aláwùúre. Kò lọ́gbọ́n nínú kéèyàn tún bẹ̀rẹ̀ síí garùn káàkiri lẹ́yìn tỌ́lọ́run bá ti fi ni sípò. Ó ṣeni láàánú pé lóde òní, bí olóṣèlú kan bá ti ní àǹfààní láti dé ipò alága ìjọba ìbílẹ̀ pẹ́nrẹ́n, ká tó mọ̀, á tún ti di ara ilé ìgbìmọ̀ aṣòfin, láti ibẹ̀, á lọ sí ilé aṣòfin aṣojú, òun yìí kan náà ni yóò du ipò gómìnà, tó bá débẹ̀ tán, á tún fẹ́ ẹ́ tẹ̀síwájú sí ipò ààrẹ. Ẹ̀kọ́ pàtàkì ni ohun tí ó ṣẹlẹ̀ sí ọba aláwùúre jẹ́ fún irúfẹ́ àwọn adarí bẹ́ẹ̀.

Yàtọ̀ fún èyí, a ríi bí ọba ṣe ṣi agbára lò nínú àlọ́ yìí. Ó ni àwọn ará ìlú lára, ó jẹ gàba lé wọn lórí, ó sì ń lò wọ́n nílò ẹrú. Ọba tó yẹ kó jẹ́ orísun àlàáfíà àti ààbò fún ìlú gan-an ló wá fi ara rẹ̀ joyè aninilára bẹ́ẹ̀. Àtunbọ̀tán àṣìlò agbára ọba yìí ni pé ìṣàkóso rẹ̀ sú àwọn ará ìlú, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kò sí ọ̀kankan nínú wọn tí ó láyà láti gbé ìkórìíra tí ó ní fún ọba lójú tàbí fi hùwà. Ṣé ọba ba lórí ohun gbogbo ni, síbẹ̀ nínú ẹni kọ̀ọ̀kan wọn, wọn ò ṣe ti kábíyèsí mọ́. Kódà, ojú ayé lásán ni àwọn ìjòyè ń ṣe pẹ̀lú rẹ̀ tí kò sì fura, kò yani lẹ́nu pé a kò rí ẹnikẹ́ni tí ó tako ìgbésẹ̀ tí àwọn awo ìlú gbé láti fọba ṣẹlẹ́yà, kí wọ́n sì rẹ́yìn rẹ̀. Ìgbẹ̀yìn ọba aláwùúre fi hàn pé àbámọ̀ ló sábà máa ń gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀ fún ẹni tí ó bá ṣi agbára lò.

Ìmọtara-ẹni-nìkan, ojúkòkòrò, owú tí kò tọ́ àti ìlara tún jẹ́ àwọn ìwà abèṣe mìíràn tí ọba yìí gbé wọ̀ bí ẹ̀wù, àlọ́ yìí fi yé wa pé ọba yìí jẹ́ olókìkí, kódà, ó kógun ja àwọn ìlú tí

ó yí i ká tí ó sì ṣẹ́gun wọn, èyí sì mú kí àwọn ọba ìlú wọ̀nyí wà lábẹ́ àjàgà rẹ̀. Àmọ́, nígbà tí òkìkí ọba Ìlúdùn kàn dé ọ̀dọ̀ rẹ̀, ó pinnu pé ire gbogbo – ọlá, òkìkí, ọrọ̀ àlùmọ́nì àti agbára ni òun gbọ́dọ̀ fi ta ọba Ìlúdùn yọ, ìtumọ̀ ìgbésẹ̀ ọba yìí ni pé òun nìkan fẹ́ ẹ́ wa gbogbo ayé máyà, Olódùmarè ò sì dá iléayé fẹ́nì kan. Èyí lè máa muni ṣe kàyéfì pé ṣé ọba yìì fẹ́ẹ́ lé Olódùmarè fúnra a rẹ̀ kúrò lórí ìtẹ́ ni? Lẹ́yìn tó jẹ ọba tán, ṣé ó tún fẹ́ẹ́ di Ọlọ́run ni? Ọba ti gbàgbé pé ẹnìkan kìí jẹ kí ilẹ̀ ó fẹ̀, ohun téèyàn bá fi wàdùwàdù ṣe kìí tọ́jọ́.

Lóde òní, ó yẹ kí àwọn adarí rí ohun tí ó ṣẹlẹ̀ sí ọba nínú ìtàn yìí gẹ́gẹ́ bí ìkìlọ̀ pàtàkì tí kò ṣeé gbójú fòdá, nítorí pé “ikú tó bá pa ojúgbà ẹni, òwe ńlá níí pa fúnni.” Olórí to ní ojúlówó ìfẹ́ fún aráàlú, tí ó sì fẹ́ẹ́ fi ẹ̀rí-ọkàn tí ó mọ́ ṣiṣẹ́ kò gbọdọ̀ ní ẹ̀mí ìfagagbága tàbí ìmọtara-ẹni-nìkan àti owú tí kò tọ́. Ẹ̀mí ìmọtara-ẹni-nìkan burú jáì, kò yẹ olórí rárá, ìdí ni pé ó máa ń tini ní ìtìkutì ni, ó sì lè tini pa. Ẹ̀mí burúkú yìí ni ó máa ń mú kí àwọn tí ó yẹ kí ó ṣèlú, kí gbogbo nǹkan gún régé, kó sì tùbà tùṣẹ di ẹni tí ó ń jẹ̀lú, èyí sì máa ń fa ọwọ́ ago ìlọsíwájú sẹ́yìn lọ́pọ̀ ìgbà. Ìmọtara-ẹni-nìkan yìí lè sọ àwọn olórí di ẹni tí kò mẹ̀tọ́-mọ̀wà. Bí ẹni tí ó ní ìmọtara-ẹni-nìkan bá tilẹ̀ mọ ohun tí ó yẹ kí ó ṣe gẹ́gẹ́ bí ojúṣe, kò níí ṣe. Ìlù “bámúbámú ni mo yó, èmi ò mọ̀ bóyá ebi ń pọmọ ẹni kankan, bámú bámú ni mo yó” ni irú wọn máa ń lù.

Ìfàsẹ́yìn tí irú ìwà yìí máa ń kó bá ètò ọrọ̀ ajé, ètò ẹ̀kọ́, ètò ìlera, ètò ìrìnnà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ kò kéré rárá. Bẹ́ẹ̀ sì rèé, ó yẹ kì àwọn olórí máa rántí, kí wọ́n sì máà fi sọ́kàn nígbà

gbogbo pé, ọba tí ó jẹ tí ìlú rójú, orúkọ rẹ̀ ò níí parẹ́, èyí tí ó sì jẹ tí ìlú ò rọgbọ, orúkọ rẹ̀ náà ò níí parẹ́. Gbogbo ọba tó ń gborí ìtẹ́ lẹ́yìn ọba aláwùúre ni wọ́n ń rọ́ ìtàn nípa ọba náà fún láti fèyí kọ́gbọ́n.

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, bí a bá perí ajá, a ó perí ìkòkò tí a fi sè é, nítorí náà, kò sí bí a ṣe le è sọ ìtàn ọba aláwùúre tí a ò níí dárúkọ ọba Ìlúdùn, ọba tí orúkọ ìlú rẹ̀ ń rò. Àlọ́ yìí fi yé ni bí gbogbo nǹkan ṣe ń lọ déédé fún àwọn ará Ìlúdùn. "Ètò-ọrọ̀ ajé Ìlúdùn gbámúṣé, àwọn oníṣòwò sì ń ṣe ìdókòwò wọn níbẹ̀." Kí ló fà á? Ìdáhùn tí a rí fàyọ ni pé onínúure ni ọba Ìlúdùn. Àpẹẹrẹ àtàtà ni ọba Ìlúdùn jẹ́ fún ẹnikẹ́ni tí ó bá wà ní ipò àṣẹ, tí ó sì jẹ́ kí ìrọ̀rùn àwọn ará ìlú jẹ òun lógún. A kò gbọ́ pé ọba Ìlúdùn kú ikú òjijì àti ikú ẹ̀sín bíi ti ọba aláwùúre, ẹnìkan ò sì lé e kúrò lórí ìtẹ́ baba rẹ̀, nítorí pé ìhùwàsí rẹ̀ bá àwọn ará ìlú rẹ̀ lára mu, ìṣàkóso rẹ̀ sì tẹ́ wọn lọ́rùn.

Ohun tí ó ṣẹlẹ̀ sí àwọn ọba méjèèjì yìí kọ́ni pé ohun tí èèyàn bá fúnrúngbìn ni yóò ká. Ìwà ọmọlúàbí tí ọba Ìlúdùn hù ni ó jẹ́ kí àsìkò rẹ̀ san tẹrú tọmọ. Bí ó ṣe jẹ́ pé kìí ṣe ọba àti àwọn ìjòyè rẹ̀ nìkan ló ń ṣèlú, tí ètò-ìṣèlú sì jẹ́ àjùmọ̀ṣe, ipa tí àwọn awo ìlú kó nínú àlọ́ yìí kò kéré rárá. Bákan náà, ẹ̀kọ́ pàtàkì wà fún àwọn olórí láti kọ́ lára àwọn awo ìlú. Nínú àlọ́-onítàn yìí, àwọn awo foríkorí, wọ́n jọ fẹnu kò, wọ́n sì fi ìmọ̀ ṣọ̀kan láti ṣe ọba aláṣejù bí ọṣẹ ṣe ń ṣojú. Ohun tí ó jọni lójú ni pé kò sí ẹni tí ó gbọ́ ohun tí wọ́n gbìmọ̀ láti ṣe, ọ̀rọ̀

náà kò sì lu síta, títí di ọjọ́ tí Olúawo ń ṣe àlàyé bí iṣú ṣe kú ati bí ọ̀bẹ ṣe bẹ ẹ́ fún àwọn ará ìlú.

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, "wiwo lẹnu awo í wo, àgbà awo kìì ba awo jẹ́." Ẹ̀rí fi hàn pé àwọn awo ìlú ṣe àmúlò òwe yìí, ìdí nìyí tí ohun tí wọ́n dì láwo ò fi tú síta débi pé yóò ta sí ọba létí. Lóde òní, ó yẹ kí àwọn aṣáájú jẹ́ ẹni tí ẹnu rẹ̀ bò, ohun tí wọ́n dì láwo kò gbọdọ̀ lu síta ṣáájú àkókò. Bí àpẹẹrẹ, ìgbésẹ̀ tí olórí kan bá fẹ́ gbé tàbí ìpàdé tì ò bá ṣe pẹ̀lú àwọn ìgbìmọ̀ kan láti kápá ìwà ọ̀daràn kí ààbò tó péye ba à lè wà lórí àwọn ará ìlú kò gbọdọ̀ di ohun tí wọn yóò máa sọ kiri láì tîì tó àsìkò láti ṣe bẹ́ẹ̀, bí bẹ́ẹ̀ kọ́, irú ètò bẹ́ẹ̀ lè di èyí tí ó forí ṣánpọ́n.

Ní ilẹ̀ adúláwọ̀, àtunbọ̀tán àwọn olórí tí wọ́n jẹ́ aninilára, ọkánjúà àti olè tún tan ìmọ́lẹ̀ sí i pé ohun téèyàn bá gbìn ni yóò ká. Ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà bí àpẹẹrẹ, láàárín ọdún 1993 sí 1998, Ọ̀gágun Sani Abacha tí ó jẹ́ ààrẹ ológun nígbà náà jẹ ayé fàmí-létè-n-tutọ́ dé góńgó, ọdún márùn-ún péré ni ó lò lórí àpèrè ìṣàkóso, àmọ́ níṣe ni iye ọdún yìí, bí ó ṣe kéré mọ, dàbí ọgọ́rùn-ún ọdún márùn-ún lára àwọn olùgbé ilẹ̀ Nàìjíríà. Kò sí ẹ̀ka àwùjọ tí Abacha kò fi ọwọ́ ìnira bà. Orípẹ́lóyè (2013:132) ṣàlàyé pé:

> The Abacha regime was a setback… for the mass of Nigerian citizens in terms of wasted economic resources and decline in political culture; this was a regime that institutionalized corruption in all segments of the society.

> Ìfàsẹ́yìn ni ìṣàkóso Abacha mú bá ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa fífi àwọn ohun àlùmọ́nì ṣòfò àti ètò ìṣèlú aláìdúró ṣinṣin, àkóso yìí ṣe àgbékalẹ̀ ìwà jẹgúdújẹrá ní ẹ̀ka àwùjọ gbogbo.

Àkíyèsí onímọ̀ tí a yọlò lókè yìí mú kí ó ṣe kedere pé kò sí 'Aráròmí' níbikíbi jákèjádò Nàìjíríà ní àkókò àkóso Sani Abacha. Kò sí àní àní pé àwọn mẹ̀kúnnù lò sábà máa ń forí fá ìyà níbi tí ìwà tani-yóò-múmi àti jẹgúdújẹrá bá ti gbilẹ̀, tí ó sì gbalé gboko.

Ìwádìí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé gbogbo òbítíbitì owó ìlú tí Abacha jí kó, tí ó sì fi pamọ́ sí àwọn ilé ìfowópamọ́ kan ní ilẹ̀ Switzerland ní orílẹ̀-èdè náà ti dá padà fún ilẹ̀ Nàìjíríà. Ìkéde kan tí ọ̀gbẹ́ni Eric Mayooraz tíí ṣe aṣojú orílẹ̀-èdè Switzerland sí ilẹ̀ Nàìjíríà ṣe lẹ́nu àìpẹ́ yìí ni ó fi ìdí òkodoro ọ̀rọ̀ yìí múlẹ̀.

Àkíyèsí Fátùrótì (2018) ṣe ìfọ́síwẹ́wẹ́ àlàyé tí ó jẹ́ ẹ̀rí máa-jẹ́-mi-nìṣó pé lóòótọ́ ohun gbogbo kìí tẹ́ olè lọ́rùn gẹ́gẹ́ bí orin àlọ́-onítàn yìí ṣe fihàn. Nínú ìjíròrò rẹ̀, Fátùrótì fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé mílíọ̀nù dọ́là lọ́nà ẹgbẹ̀rún kan àti mẹ́tàléláàádọ́rin (1,073 million dollars) ni iye owó tí orílẹ̀-èdè Switzerland dá padà fún orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Onímọ̀ yìí là á mọ́lẹ̀ pé:

> Tí a bá sẹ́ mílíọ̀nù dọ́là lọ́nà ẹgbẹ̀rún kan àti mẹ́tàléláàádọ́rin sí owó Náírà ilẹ̀ Nàìjíríà, ó ju owó àbá ìṣúná ìpínlẹ̀ mẹ́rìnlá mìíràn lọ. Ó tó kọ́ pápákọ̀ òfúrufú mẹ́fà, ó tó kọ́ yunifásítì ńlá ńlá mèje, ó tó kọ́ ilé ìwòsàn àrágbáyamúyamù

> márùn-ún, ó tó la ọ̀nà ọlọ́dà ẹlẹ́gbẹ̀rún mẹ́rin kìlómítà yíká orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, ó tó bọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ mílíọ̀nù mẹ́tàdínlógún tó wà káàkiri ìpínlẹ̀ tó wà ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà fún ọdún méjì gbáko. Bí wọ́n bá ń pín owó náà, ẹgbẹ̀ta náírà lọ́nà ẹgbẹ̀rún (₦600,000) ni yóò kan ọmọ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà kọ̀ọ̀kan.

Àkíyèsí onímọ̀ yìí ṣe àfihàn ìhùwàsí onímọ̀-tara-ẹni-nìkan tó burú jáì. Láì fepo bọyọ̀, ìwà àìnírònú àti ìwà ọ̀dájú gbáà ni Abacha hù pẹ̀lú bí ó ṣe yàn láti wa gbogbo ọrọ̀ Nàìjíríà máyà láàárín ìwọ̀nba sáà péréte tí ó lò lórí àléèfà.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn olùgbé ilẹ̀ Nàìjíríà ni Abacha fi ìwà ọ̀kánjúà àti olè sọ di àwọn tí ó wà bí aláìsí nítorí pé "bí wọ́n ṣe ń ṣiṣẹ́ bí erin ni wọ́n ń jẹ̀jẹ ẹ̀lírí." Yàtọ̀ fún èyí, Abacha ṣi agbára lò débi pé bi ó ṣe ń sọ àwọn tó rí gẹ́gẹ́ bí ọ̀tá àti alátakò sí ọgbà ẹ̀wọ̀n, bẹ́ẹ̀ ló ń pa àwọn mìíràn nípakúpa bí ẹni pẹran. Ọpẹ́lọpẹ́ ikú àìròtì tí ó pa ojú rẹ̀ dé ni ó sọ àwọn ará ìlú di òmìnira.

Bí a bá fi ìṣàkóso ọba inú àlọ́-onítàn, tíí ṣe ọba aláwùúre wé ìjọba Abacha, a ó ṣe àkíyèsí pé ọmọ iṣẹ́ lásán ni ọba inú àlọ́ yìí jẹ́ fún Abacha. Ìjọba Abacha dá àwọn ènìyàn lóró débi pé nígbà tí ìròyìn ikú ẹ̀sín tí ó kú kàn káàkiri, tí àwọn ènìyàn sì rí àrísá pé òótọ́ ni, àwọn kan ò dúró donílù kí wọ́n tó fẹsẹ̀ rajó, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ló sì fọ́n sí ìgboro pẹ̀lú tìlùtìfọn àti orin ọpẹ́. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní "ẹni tó bá ṣohun tẹ́nìkan kò ṣe rí, ojú rẹ̀ yóò rí ohun tí ojú ẹnìkan kò rí rí." Ṣáájú àti lẹ́yìn ikù ààrẹ Abacha a kò tíì rí olórí tí gbogbo ará ìlú yọ ayọ̀ ikú

rẹ̀ lọ́nà tó kàmàmà bẹ́ẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé nǹkan ìbànújẹ́ ni ikú jẹ́, ojúlówó ayọ̀ àti òmìnira kúrò lọ́wọ́ àṣìlò agbára ni ikú Abacha ni tirẹ̀ jẹ́ fún àwọn olùgbé ilẹ̀ Nàìjíríà. Àtunbọ̀tán ọba aláwùúre àti Abacha fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ikú àìtọ́jọ́ àti ikú ìyà ni yóò máa jẹ́ ìpín àwọn alákòóso tí wọ́n bá yàn láti ya ìkà àti ọ̀jẹ̀lú. Ìfanilétí ni ìgbẹ̀yìn àwọn méjèejì jẹ́ fún ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn ọmọ ìyá wọn tí wọ́n wà ní ẹ̀ka àkóso gbogbo.

## Àgbálọgbábọ̀

Àlọ́-onítàn tí a pe àkọlé rẹ̀ ní *Ọba Aláwùúre* ni a lò gẹ́gẹ́ bí détà fún iṣẹ́ ìwádìí yìí. Àlọ́ yìí ni a lò gẹ́gẹ́ bí dígí aṣàfihàn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ Yorùbá ayé àtijọ́. Àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tí a jíròrò lé lórí ni ogun jíjà àti ìṣèlú ilẹ̀ Yorùbá. A wo díẹ̀ lára iṣẹ́ tí àwọn ènìyàn ti ṣe lórí àlọ́-onítàn Yorùbá. A ṣe àtúpalẹ̀ bí ìjẹyọ ogun jíjà àti ètò-ìṣèlú inú àlọ́ ṣe bá ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ Yorùbá ayé ọjọ́un mu. A sì jíròrò lórí àwọn ẹ̀kọ́ pàtàkì tí àwọn olóṣèlú òde-òní lè kọ́ láti inú *Ọba Aláwùúre*. Tíọ́rì tí a ṣàmúlò fún àtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí ni tíọ́rì Karl Marx. Orí èrò tí iṣẹ́ yìí gúnlẹ̀ sí ni pé àlọ́-onítàn Yorùbá jẹ́ àká ìmọ̀ tí a ṣe ọ̀nà ìgbé-ayé wọ́n ní àwùjọ Yorùbá ayé ọjọ́un lọ́jọ̀ sí.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Adéoyè, C.L (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá.* Ìbàdàn: Oxford University Press Ltd.

Agbájé, J.B. (2013). *Àlọ́ nínú Àṣà Yorùbá.* Iléṣà: Elyon Publishers.

Àjàyí, F.T àti Atọ́lágbé, A.A (2015). "Ìfihàn Ètò Ìṣèlú Ìbílẹ̀ Yorùbá Nínú Ìwé Ìtàn Àròsọ Ògbójú Ọdẹ Nínú Igbó Irúnmọlẹ̀ àti Igbó Olódùmarè." In Rájí, S.M. (ed.) *Èdè, Àṣà àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá.* (pp 340-348) Ìbàdàn: Masterprint Publishers.

Àjùwọ̀n, J. (2017). "Ìtúpalẹ̀ Àṣàyàn Oríkì Àwọn Akọnikùnrin àti Akọnibìnrin Yorùbá ní Ìwọ̀ Oòrùn Gúúsù Orílẹ̀-Èdè Nàìjíríà." Unpublished Ph.D. Thesis, Department of Linguistics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ile-Ifẹ̀.

Akínyẹmí, A. (1987). "Déńrelé Adéètìmíkàn Ọbasá (1927-1945) Akéwì Alárọ̀jinlẹ̀." M.A. Thesis, Department of African Languages and Literatures, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Àlàmú, G. (2013). "Ipò Àṣà Nínú Ìṣèlú ati Ààbò Orílẹ̀-Èdè Nàìjíríà." *Yorùbá Journal of the Yorùbá Studies Association of Nigeria*, Vol. 7, No. 2, pp 35-53.

Arárọba, T.O. (2015). Àgbéyẹ̀wò Ètò-Ìṣèlú Yorùbá Nínú Àṣàyàn Àlọ́-Àpagbè Yorùbá. Unpublished M.A Thesis, Department of Linguistics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Babalọlá, A. (1973). *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá I.* Ìbàdàn: Oxford University Press Plc.

Babalọlá, A. (1979). *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá II.* Ìbàdàn: Oxford University Press Plc.

Dáramọ́lá O. àti Jéjé, A. (1967). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press and Book Industries (Nig.) Ltd.

Fánilọ́lá, K. (1990). “Contemporary Yorùbá Oral Poetry.” Ph.D. Thesis, Department of Linguistics and African Languages, University of Ìlọrin, Ìlọrin.

Fátùrótì, O.R. (2018). “Kíkó Ọ̀rọ̀ Jọ Lọ́nà Àìtọ́” Pépà Àjọrò tí a kà lórí Rédíò Orísun, Òkè-Ìtasẹ̀, Ilé-Ifẹ̀ ní Ọjọ́ Kejì, Oṣù Keje, Ọdún 2018.

Láyẹni, O. (1978). “Ètò Ogun Jíjà Nílẹ̀ Yorùbá” In Ọlájubù, O. (ed.) *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá.* (pp. 192-201). Ìbàdàn: Longman (Nig.) Ltd.

Ògúnpolú, B. (1986). “Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ lórí Àlọ́ Apagbè.” In Ọlábímtán, A. (ed.) *Aáyan Ọ̀mọ̀ràn Lórí Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá.* Àpérò Kejì ní ìrántí J.F. Ọdúnjọ (pp 35-56). Lagos: Mark of Time Ltd.

Ògúnṣínà (1987). “The Sociology of the Yoruba Novel: A Study of Isaac Thomas, D.O. Fagunwa, and Ọládẹ̀jọ Òkédìjí.” Ph.D. Thesis, Department of Lingusitics and African Languages, University of Ìbàdàn.

Ọlájubù, O. (1978). “Ìjọba Ìbílẹ̀ Láyé Àtijọ́” In Ọlájubù, O. (ed.) *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá.* (pp. 89-96). Ìbàdàn: Longman (Nig.) Ltd.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí, J.A. (1997). Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lò-Èdè. Òṣogbo: Tanímẹ̀hìn-ọ̀la Press.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí, J.A. (2014). *Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lò-èdè.* Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press.

Orímóògùnjẹ́, O.C. (1996). *Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá.* Lagos: Karohunwi Nigeria Enterprises.

Orípẹ́lóyè, H. (2013). "Postcolonial Exilic Narration in Fẹ́mi Òjó-Ade's Exile at Home." Marang: *Journal of Language and Literature,* vol. 23:129-142.

Oyèdèjì, V.A. (2017). "Ìtúpalẹ̀ Ìtàn Àlọ́ inú Àṣàyàn Orin Fújì Síkírù Àyìndé Barrister àti Orin Jùjú Ebenezer Obey." Unpublished Ph.D Thesis, Department of Linguistics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Oyètádé, J. (2009). "Ìtàn Àròsọ Yorùbá àti Ètò-Ìṣèlú Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà". *Ìtànsán Oòduà, Jọ́nà Ẹgbẹ́ Olùkọ́ Èdè Yorùbá.* 15-23.

Oyèwọlé, B. (1996). "Àwọn Àyípadà tó ti dé bá Àṣà Ìṣèlú láàrin Ẹ̀yà Yorùbá". *Yorùbá Gbòde – Jọ́nà Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè àti Àṣà Yorùbá, Nàìjíríà.*

Rájí, S.M. (2014). "Àgbéyẹ̀wò Ojú Àmúwayé àti Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá nínú Orin Mùsùlùmí ní Ilẹ̀ Yorùbá." Unpublished Ph.D. Thesis, Department of Linguistics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.